# A MÚ PAULU NI JERUSALẸMU

**Iṣe Awọn Apọsteli 21:1-40; 22:1-30; 23:1-35**

**ẸKỌ 370 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ọlọrun kò fun wa ni ẹmi ibẹru; bikoṣe ti agbara, ati ti ifẹ, ati ti inu ti o yè koro" (2Timoteu 1:7).**

**I Paulu Rin Irin-Ajo Lọ si Jerusalẹmu**

1 Paulu ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ̀ duro fun ọjọ meje ni Tire, Iṣe Awọn Apọsteli 21:1-4

2 Ni Tire awọn ọmọ-ẹyin sọ fun Paulu nipa Ẹmi, pe ide ati iya duro de e ni Jerusalẹmu, Iṣe Awọn Apọsteli 21:4-7

3 Ni Kesarea, a tipa Ẹmi Ọlọrun kilọ fun Paulu pe awọn Ju yoo de e ni Jerusalẹmu, Iṣe Awọn Apọsteli 21:8-14; 20:22, 23

**II Paulu Dé Jerusalẹmu**

1 Paulu royin iṣẹ-iranṣẹ ré fun Jakọbu ati awọn àgba ijọ, Iṣe Awọn Apọsteli 21:15-20

2 Awọn alàgba ni ki Paulu jẹ́ ẹ̀jẹ́ pẹlu awọn ọkunrin mẹrin miiran lati le tu awọn Ju loju, o si ṣe bẹẹ, Iṣe Awọn Apọsteli 21:20-26

3 Awọn janduku eniyan laaarin awọn Ju mú Paulu, ṣugbọn awọn ọmọ ogun Romu gba Paulu silẹ ki a to pa a lara, Iṣe Awọn Apọsteli 21:27-37

**III Ẹri Paulu ati Ìsọ-sẹ́wọ̀n rẹ̀**

1 A fun Paulu ni anfaani lati bá awọn Ju sọrọ, Iṣe Awọn Apọsteli 21:38-40; 22:1-21

2 Awọn ara Romu ni o tọju Paulu di ọjọ keji, ni akoko ti o tun ni anfaani lati sọ ẹri rẹ̀ fun olori alufaa ati igbimọ, ati niwaju awọn ara Romu, Iṣe Awọn Apọsteli 22:22-30; 23:1

3 Awọn Ju tun gbiyanju lati pa Paulu, eyi mú ki awọn ọmọ-ogun mu un tọ Fẹliksi Baalẹ lọ lati tubọ wadii ọ̀rọ lẹnu rẹ̀, Iṣe Awọn Apọsteli 23:2-35

## ALAYE

### Paulu Ọkunrin Naa

Awọn ori iwe mẹjọ ti o kẹyin ninu Iṣe Awọn Apọsteli sọ fun ni nipa awọn nnkan wọnni ti o ṣẹlẹ si Paulu Apọsteli nigba ti o kù diẹ ki o fi ayé yii silẹ. Itara ti o leke ninu ọkàn Paulu ni lati waasu Kristi fun awọn eniyan wọnni ti kò ti mọ ohunkohun nipa Rẹ̀. Paulu fi gbogbo ọkàn rẹ jì fun isin Ọlọrun; iru ifọkansin ati itara gbigbona pẹlu aisinmi lẹnu iṣẹ Oluwa yii mu ki Ẹmi Mimọ́ mi si awọn oju iwe wọnni ninu Bibeli ti o sọ nipa igbesi-ayé ati iṣe ọkunrin yii, wọn si wà fun imisi fun awọn iran-iran ti n bọ̀. Paulu mú ki ifẹ nla ti o ni si Ọlọrun di mimọ̀ nigba ayé rẹ̀; ati nitori akọsilẹ igbesi-ayé rẹ̀ ninu Bibeli, igbesi-ayé rẹ̀ ni ìmísí rere fun ọ̀pọlọpọ eniyan lati igba naa; ati oun gẹgẹ bi Abẹli, bi o tilẹ kú o n fọhùn sibẹ.

### Irin Ajo ti a ti Yàn

Paulu ni itọni Ẹmi Ọlọrun lati tun pada lọ si Jerusalẹmu. Ninu ile ẹjọ ti o ga ju lọ ni ijọba ilẹ Romu, ani ti Kesari, ni o fi pari irin ajo naa.

Bi o tilẹ jẹ pe ni gbogbo ilu ti o n dé ni Ẹmi Ọlọrun ti n kilọ fun un nipa iyọnu ti n duro de e ni Jerusalẹmu lati ọwọ awọn Ju, sibẹ Paulu kò mi ọkàn lati lọ. Ọlọrun pe Paulu lati waasu Ihinrere Jesu Kristi fun awọn Keferi, ṣugbọn ọkàn rẹ̀ n gbina nigba gbogbo fun igbala orilẹ-ède rẹ̀, ani awọn Ju. Ọkàn rẹ̀ fà gidigidi lati pada lọ si Jerusalẹmu lati sọ ọ̀rọ ẹri rẹ̀ fun awọn Ju nipa awọn nnkan nla ti Kristi ti ṣe fun un ati ti Kristi yoo si ṣe fun wọn pẹlu bi wọn ba le gba orukọ Rẹ̀ gbọ́. Paulu pinnu lati sọ ẹri rẹ̀ fun wọn ohunkohun ti o ba tilẹ le dé nipa ṣiṣe bẹẹ. Paulu mọ riri ẹri ẹlẹṣẹ ti a fi Ẹjẹ Jesu wẹnu, ati bi o ti

niyelori tó, o si mọ̀ lati inu iriri pe kò si ẹni ti o le gbọ́ wọn ti ki yoo ni igbọgbẹ ọkàn. Kò si ohun ti o daju ju ẹri awọn eniyan lọkunrin ati lobinrin ti o mọ̀ dajudaju pe wọn ti rekọja lati inu òkunkun sinu imọlẹ ayeraye. Iwaasu ti o ni aṣẹ ni iru awọn ẹri bawọnyi jẹ́, eyi ti o ni ifohun si ati ifororo yàn Ẹmi Mimọ Ọlọrun. Kò si ẹni ti o gbọ́ wọn ti o le gbagbe bọrọ.

Iyipada Paulu ti lu igi nla mọ ilana ẹsin awọn Ju to bẹẹ ti awọn ti n tẹle ilana naa kò fi dariji Paulu. Lati padanu ọ̀kan ninu awọn olori wọn si ọdọ Kristi jẹ́ ẹdun nla ni ọkàn wọn, nitori eyi ni wọn fi fẹ pa Paulu bi “asọrọ-odi si igbekalẹ ẹsin wọn.” Ewu nla gbaa ni lati lọ si aarin awọn eniyan wọnyii ki o ba le sọ ẹri rẹ̀ fun wọn. Paulu fẹran awọn eniyan orilẹ-ède rẹ tó bẹẹ ti o fi ni ifẹ lati sọ ẹmi rẹ̀ nù nitori wọn, bi o ba gbà bẹẹ (eyi ti a si fi agbára mu un ṣe), ni ireti pe ki wọn ba le là. Ṣaaju akoko yii, Paulu wi bayii nipa igbala awọn ara ilu rẹ: “Mo fẹrẹ le gbadura pe ki a ké emi tikarami kuro lọdọ Kristi, nitori awọn ará mi, awọn ibatan mi nipa ti ara” (Romu 9:3). O si tun wi bayii pe, “Ifẹ ọkàn mi ati adura mi si Ọlọrun fun Israẹli ni, fun igbala wọn” (Romu 10:1). Paulu, fi hàn nipa fi fi ẹmi rẹ̀ fun Ihinrere pe ohun ti oun wi ki i ṣe ọrọ lasan bi kò ṣe ọrọ ti o ti inu ọkàn ti ifẹ ti n jó geregere lati ri i pe awọn eniyan rẹ̀ wá si imọ igbala Kristi.

Bi o tilẹ jẹ pe irin-ajo Paulu si Jerusalẹmu nipa eyi ti a fi sinu tubu ati eyi ti o mú ikú de ba a le dabi ohun wèrè loju awọn ẹlomiran, ṣugbọn awa mọ̀ lati inu Iwe Mimọ́ pe Ọlọrun duro ti i ninu gbogbo iṣoro rẹ̀, O si fun un ni iṣẹgun nlanla; ati nikẹyin gbogbo rẹ̀, Ọlọrun mu un lọ sọdọ ara Rẹ̀.

Paulu fi gbogbo igbẹkẹle rẹ̀ sinu Ọlọrun fun aabò; bi o tilẹ jẹ pe kò sọ ọ̀rọ kan naa ti Jobu sọ, sibẹ bakan naa ni igbagbọ rẹ̀ ninu Ọlọrun. “Bi o tilẹ pa mi, sibẹ emi o ma gbẹkẹle e” (Jobu 13:15).

**Ẹri ati Iṣẹgun**

Jesu wi pe: “Nwọn o yọ nyin kuro ninu sinagọgu; ani, akokò mbọ̀, ti ẹnikẹni ti o ba pa nyin, yio rò pe on nṣe isin fun Ọlọrun” (Johannu 16:2). O wi pẹlu pe: “Nwọn o nawọ́ mu nyin, nwọn o si ṣe inunibini si nyin, nwọn o fi nyin le awọn oni-sinagọgu lọwọ, ati sinu tubu, nwọn o mu nyin lọ sọdọ awọn ọba ati awọn ijoye nitori orukọ mi. Yio si pada di ẹri fun nyin. Nitorina ẹ pinnu rẹ̀ li ọkàn nyin pe ẹ ki yio ronu ṣaju, bi ẹ o ti dahun. Nitoriti emi ó fun nyin li ẹnu ati ọgbọ́n, ti gbogbo awọn ọtá nyin ki yio le sọrọ-òdi si, ti nwọn ki yio si le kò loju” (Luku 21:12-15).

Ikilọ ti o le ni eyi, boya, fun ọ̀pọlọpọ awọn ti yoo doju kọ awọn nnkan ti Jesu sọ wọnyii, ṣugbọn a ṣeleri iṣẹgun ologo fun wọn nipa iranlọwọ ti oore-ọfẹ Ọlọrun. Jesu wi pe Oun kò dá wà ṣugbọn Baba wà pẹlu Oun nigba gbogbo; bakan naa ni o ri fun awọn ọmọlẹyin Rẹ̀, pe awọn pẹlu kò dá wà. Jesu wi pe ayé yoo jẹ́ ọtá awọn Onigbagbọ́ ṣugbọn O sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ki wọn má ṣe bẹru, nitori ti Oun ti ṣẹgun ayé.

Nigba ti Johannu Ayanfẹ ni erekuṣu Patmo ri iran ohun ti yoo ṣẹlẹ nigba ikẹyin, o ri awọn ti a sọ nipa ti wọn pe: “Nwọn si ṣẹgun rẹ̀ nitori ẹ̀jẹ Ọdọ-Agutan na, ati nitori ọ̀rọ ẹri wọn, nwọn kò si fẹran ẹmi wọn ani titi de ikú” (Ifihan 12:11). O jẹ́ inudidun Ọlọrun pe Paulu yoo jẹ́ ọ̀kan ninu awọn ẹgbẹ́ nla naa ti o fi ẹjẹ ara wọn di ẹri ati ijolootọ wọn si Oluwa.

Paulu ti sọ itan nla ti Jesu ati ifẹ Rẹ̀ ká gbogbo ilẹ ọlaju ni gbogbo ayé; ati nigba ti igbesi-ayé rẹ̀ n kù fẹẹfẹ, o tun ni lati sọ ọ̀rọ ẹri rẹ̀ niwaju awọn ọba ati ijoye. Wọn ti kọ Ọba Ogo silẹ wọn yoo tun kọ Paulu silẹ pẹlu; ṣugbọn oloootọ ni Ọlọrun, aanu Rẹ̀ si wà lati iran dé iran. Lẹẹkan si i, O tun n rán ọ̀kan ninu awọn ti Rẹ̀ lati sọ itan naa ki awọn eniyan ba le ronupiwada ẹ̀ṣẹ wọn ki wọn le ri ìye ainipẹkun gbà. Kò si ẹni ti o gbọ́ iwaasu Paulu ti yoo sọ pe oun kò i ti gbọ nipa Ihinrere. Bi o tilẹ jẹ pe yoo jẹ́ atunsọ ọ̀rọ ti wọn ti wi ṣaaju, ni ọ̀rọ ati ni iṣe, pe wọn kò fẹ ki ọkunrin yii (Kristi) ki o jọba lori wọn, sibẹ, Oun jẹ́ oloootọ, Oun kò fẹ ki ẹnikẹni ki o ṣegbé, ṣugbọn ki gbogbo eniyan le ni iye ainipẹkun nipa Jesu Kristi Oluwa.

## AWỌN IBEERE

1. Bawo ni Paulu ṣe mọ̀ pe ide ati ipọnju n duro de oun ni Jerusalẹmu?
2. Ki ni ipinnu Paulu nipa irin-ajo rẹ̀ lọ si Jerusalẹmu?
3. Ki ni ṣe ti awọn alàgbà ti o wà ni Jerusalẹmu fi n fẹ ki Paulu jẹ́ ẹ̀jẹ́?
4. Ki ni ṣe ti Paulu fi ṣe bẹẹ?
5. Ki ni ṣe ti awọn Ju fi gbiyanju lati pa Paulu?
6. Bawo ni a ṣe yọ Paulu kuro ninu ipalara?
7. Ki ni ṣe ti a fi mu Paulu lọ si iwaju Fẹliksi fun ibileere ọrọ?